# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 564 WEDNESDAY, MARCH 25, 1964 (2D)


N400

## Eniti O Ji Basikulu Gbe Wewon Odun Meji

YABA:— Oju gba gbogbo enia ti fun Ọdọmọdekunrin kan, Musibawu ẹni ọdun mejilelogun ti awọn Ọlọpa sọ pe ko ni ibugbe kan, nigbati awọn Ọlọpa mu wa siwaju Adajọ Agba Ile ẹjọ kekere fun ẹsun ole jija ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun Ile ẹjo wipe, Ọdaran na lọ si ọdọ Ọgbẹni Ariyọ Sanusi ti o ngbe nọmba 55, Old Yaba Road, Ebute-Mẹtta, o si ji basikulu rẹ meji gbe ni oṣu keji ọdun yi.

Nigbati ọkunrin na wa awọn basikulu rẹ ti o fi nṣiṣẹ ti ko si ri ki odaran ti o gbe wọn lọ gbewọn pada mọ, ni o ba wa fi ọran na sun ọlọpa ni tesan.

Nigbati awọn ọlọpa na ti nwa ọdaran na ni awọn ba ri on ati awọn basikulu mejeeji, nibiti nwọn lero pe o fẹ ta wọn fun awọn alarobo ṣugbọn awọn ọlọpa ragabu rẹ.

Nigbati ọdaran na rojọ, ti o si gba wipe on jẹbi ẹsun ole ti awọn ọlọpa fi kan on pe on ji basiku meji gbe, ti iye owo wọn jẹ pọnun mẹrinlelogun (24) ni adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn ọdun meji jura.

# IGBIMỌ MUSULUMI EKO ṢE ARIYA FUN AWỌN ERO MẸKA

EKO:— A kole fẹnu rohin ariya alarinrin kan ti awọn ọmọ ẹgbe Igbimọ Musulumi Naijiria (United Musulimi Council of Nigeria) ti ẹka Eko ṣe tan fun awọn ọmọ ẹgbẹ wọn l'ọkunrin ati l'obinrin ti nwọn nmura lati lọ si Mẹkka ati Mẹdina ni ọdun yi ninu ile Sinima kan to mbẹ leti ọja Ita-Faji l'eko ni irọlẹ ọjọ kọkandinlogun oṣu March 1964.

Ki o to to asiko ti nwọn fi ipade ariya na si ni ile Sinima na ti kun ṣọṣọ depo ti ofi jẹ wipe bi enia baju abẹrẹ silẹ abẹrẹ na ko ni le delẹ larin wọn, enia pọ to bẹ ti Aga ijoko ile Sinima na ko fi to ioko.

Ariya ọjọ na bẹrẹ pẹlu adura lati ọwọ Alfa Tẹsilimi Nasiru Ọgbẹni A A. Abayomi ni ẹniti o fi Alhaji T. S Calfos han gẹgẹ bi alaga ariya ọjọ na.

Bi ariya ọjọ na ti larinrin to Alfa F. A. Yusufu lo sọ gẹgẹbi Mẹkka ati Mẹdina ti ri osi tun sọ ohun to ti ṣẹlẹ lati igba aiye Anabi Ibirahim yi ti o fi nmu ẹnikẹkẹni l'okan lati lọ ati pe o tun sọ iru ibukun to mbẹ fun ẹniti oba foju kan ile Mimo na.

Lẹhin ọ p ọ l ọ pọ alaye, Alfa Yesufu sọ wipe kosi ohun to mbẹ lori irin Mẹkka ati Mẹdina to ju igbagbọ Ododo lọ.



Alahji A. F Masha

fun idagbasoke isin Ojiṣẹnla Muhammed.

Lẹhin alaye rọ, o tun fi Alhaji Calfos han gẹgẹbi ẹniti Ọlọrun da sinu ilẹ Yoruba, ṣugbọn ti gbogbo iṣe si rẹ farajọ ti awọn Larubawa.

Alhaji Yakubu fi nye gbogbo enia to pejọ si bi ariya ọjọ na wipe, o di ọdun kọkandinlogun ti Alhaji Calfos ti nlọ si Mẹkka ati Mẹdina.

O ni, ko si ọdun kan ti yio lọ ti ko ni mu to enia mẹrin-merin lọ lati apo ara rẹ, ati pe, ẹnikẹni ti o ba tẹ le e lọ gẹgẹbi iṣẹ rẹ ni ko ni mọ iya ati iponju to mbẹ nilẹ Mẹkka ati Mẹdidina.

Ni a fi kun, Alhaji Calfos na dide, o ni ki gbogbo awọn enia ti o nmura lati

Wo Oju Ewe Kẹfa

### YASIN ATI HUTUBA

Ninu ariya na Imam Oseni Ope (Olohun iyọ) lo ke Yasin ati Hutuba fun lilọ ati pipada bọ awọn ọmọ ẹgbẹ na to nlọ si Mẹkka ati Mẹdina lọ'dun yi, Alhaji Fasasi Tukura si fi adura kikun kin Yasin na lẹhin.

Lẹhinna, Alhaji Yakuba (Akọwe agba Igbimọ na dide, o sọ orisirisi iṣẹ ti ẹgbẹ Igbimọ Musulumi na nṣe

## Oloye Irọko Di Olori Gbogbo Awọn Ele'gun

EKO:— Irohin ko to afojuba ni ti inawo ifi jẹ oye Olori gbogbo awọn elegungun ilu Eko ati agbegbe rẹ ti nwọn ṣe ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ninu ile Oloye na ni nọmba 38 Beckley Street, Ararọmi Odo Eko ni deede agogo mẹrin irọlẹ.



OLOYE D. O. IRỌKO

Irohin ti ye wa pe nigbati o ti ku bi ọjọ mẹta ti awọn o ṣe inawo na ni ogunlọgọ awọn enia ti bẹrẹsi ide lati Abẹokuta, Ibadan Ọyọ, Ijẹbu-Ode, Idọgọ, Ikorodu, Shagamu, Otta, Agege, Mushin, Ikeja, Ebute-Metta ati bẹẹ lọ.

Nigbati ọjọ na pe, ni deede agogo meji ọsan ni ilu bata, dundun kannamago, ati apala ti bẹrẹsi dun ti gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ati awọn egungun njo kariri gbogbo adugbo bi kokoro.

Gbogbo awọn elegungun ilu Eko ati agbegbe rẹ ni nwọn tan aṣọ ju wọn wa sibi ifi jẹ Oye na. Awọn enia na sọ wipe nigbati awọn wo gbogbo awọn agba ojẹ ti o wa ni Eko ati agbegbe rẹ, ko tun si ẹniti Oye na to si mọ, bikoṣe Oloye D. O. Irọko.

Oloye Irọko yi ni o ti jẹ Olori gbogbo awọn oniṣegun ilu Mushin ati agbegbe rẹ ri, nwọn si fi jẹ Oye Alapinni.

Wo Oju Ewe Kẹfa

# IGBOMINA, EKITI ATI ỌFFA, ETI NYIN MELO?

**Lati ọwọ Ọlọrun-Lo-Ri'nu**

Mo ki gbogbo ọmọ bibi ilẹ Igbomina, Ọffa Ekiti ati Odo-Ogun, Ọlọrun Ọba Ọga Ogo yio wa pẹlu nyin yio si ran nyin lọwọ yio si gbe nyin leke awọn ọta nyin yio siju Anu wo nyin. Ọlọrun yio jẹki Ominira ilẹ wa ko bọsi laipẹ jọjọ eyi ni Division ti a nbere fun.

Ki nto ma ba ọrọ mi bọ, mo ni lati kọkọ dupẹ lọwọ ọgbẹni wa M. A Ọdẹkunle ẹniti o kọkọ bẹrẹ si ọrọ yi ni bẹrẹ oṣu July 1959 ti o nkọwe jade kikankikan nipa Division yi.

Bi otilẹ jẹ pe o ni alatako nigbana, ṣugbọn nisisiyi, Ọlọrun gbọ igbe rẹ gbogbo ilẹ wọnyi lo si faramọ Division na loni, mo dupẹ pupọ lọwọ rẹ. ọgbọn ti Ọlọrun fun ẹ nigbana ti ẹfi nṣe alaye lorişirişi idi ti o fi yẹ ka ni Division na Ọlọrun yio tubọ ma fun ẹ ni ọpọlọ pipe siwaju ati siwaju.

Bakanna ni mo tun nilati dupẹ lọwọ gbogbo awọn Igbomina lasiko yi pataki fun ẹgbẹ NPC atijọ, fun iro nu piwada wọn, ti awọn na faramọ ọrọ Division yi



**Ọgbẹni M A Ọlanrewaju**



Ọgbẹni TITUS BALOGUN



Ọgbẹni Ọdẹkunle

Ọrọ pọ, ṣugbọn enia ko ni sọ ju bayi lọ ki Ọlọrun maşe jẹka ri apada si buruku mọ ti yio tun mu nyin pada si ọdọ awọn Ilọrin, akoko ti Ọlọrun lo to, Ọlọrun ko ni doju ti nyin o.

AGBADO LABẸ APARO

Pataki ọrọ mi si gbogbo ẹnyin Igbomina, Ọffa, ati Ekiti nipe, o yẹ kaşọra lasiko yi dada ko ni dara ka fi aparo si abẹ ka si ma gbin agbado bi bẹ kọ gbogbo agbado ti ẹgbẹ na ba gbin Ọlọrun le şe ki agbado na hu jade dada.

Idi ti o mu mi sọ eleyi ni pe mo gba pe ẹgbẹ mẹta lo wa ni ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti nisiyi, awọn ẹgbẹ kan nba Ilọrin ja pe ka gba Division ti wa kuro labẹ wọn awọn ẹgbẹ kan tun nbawọn Ilọrin, şe ọrẹ eleyi buru.

Nipa biba awọn ẹgbẹ yi şe ọrẹ awọn Ilọrin tu bọ ni aşoju si ni, eleyi buru gan ni, fun apẹrẹ mo lọ si irinajo kan laipẹ yi, nigbati mo de Ajassẹpo, mori ọkọ awọn Ilọrin ti o nti ọna Ọffa bọ, ero mi ni wipe, nwọn o kọja si ọna Ilọrin şugbọn wọn fori le ọna Oro, emi na tel wọn

Nigbati a de Oro nwọn duro diẹ, emi na nsimi, şugbọn ngo mọ ibiti nwọn wo, nigbati a tun kuro nibẹ a gbera a lọ si Edidi Oke-Ona, a tun duro nibẹ, emi na duro si idi igi ọdan, pẹlu mọto ayọkẹlẹ mẹta ti awọn Ilọrin nghe kiri wọle kan lọ nibẹ, bayi ni nwọn nşe kiri ilẹ wa, nisisiyi o yẹ ka şe eto ki gbogbo wa le wa loju kanna.

Ẹ maşe fi ibinu ẹ kuku ge igi arere, bo tilẹ jẹ pe olukuluku ilu lo ri iyọnu, tabi ẹgbin ti awọn N.P.C. Atijọ fi jẹ nwọn niya, Ọtẹ ẹgbẹ lo fa, şugbọn nisisiyi awọn na ti ronu piwada

Ki awọn agbalagba wa ni ilẹ Igbomina jọwọ ki nwọn şeto lati pari gbogbo edeaiyede ti mbe larin awọn N.P.C. ọdọ ati awọn N.P.C. agba.

Mo si mọ daju pe awọn enia ilẹ Igbomina ni agbalagba ko ni pari ọrọ na ti rara.

Mo si ka awọn agbalagba wọnyi si pe awọn ni N. A, Igbomina Ọffa ati Ekiti, nwọn ko le pari ọrọ na ti, nitori Igbomina ki şe Alabosi

Nitorina, lakotan, mo kesi gbogbo ẹnyin agbalagba ilẹ Igbomina, ki ẹ tete pari ọrọ na, ki ẹ fi ti (Western) Ijọba Iwọ-Orun kẹ ma fi şe jigi, Ọlọrun ko ni ba işẹ wa jẹ o.

Ajeji ọwọ kan ki igbe ẹru dori o, Ẹnyin agbalagba, ẹ maşe foju dogẹ, tẹ ba ri, kẹ maşe sọ pe ẹ o ri o, o jọwọ nyin o.

Şugbọn mo mọ ohun kan daju pe ni atilẹhin Ọlọrun ao gba Division.

Ilọrin ti yọ pasan lara wa, lati maa fi na wa ni şugbọn gbogbo ete nwọn Ọlọrun yio sọ di ofo.



Ọgbẹni J. O. Ọlawọyin


AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

Réf. N° 55 PHOTO

Free illustrated catalogue on demand



PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque

WINDSOR

19, Avenue de Lérins - Cannes, France

# IWE SI OLOTU

## Ẹ ku Iṣẹ Wa Yi Ọgbẹni Yemitan

Olotu, Idunnu ni yio jọ fun mi ti ẹba le jẹ ki iwe mi yi jade ninu Iwe Irohin yi oloyin momọ. Mo fẹ lati fi iwe wa dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ọladipọ Yemitan fun akitiyan rẹ lati le kọ Iwe lori Ijala are Odẹ eyi ti Ọgbẹni na ṣe fun kika awọn ọmọ Yoruba.

Bi mo se ri ka ninu Iwe Irohin Imọlẹ ni mo sare lọ ra Iwe na nile iawẹ kan

Bi mo ti nkaa, odabi ẹnipe ẹni na ti di Ọdẹ ti onsun Ijala na.

Mo fẹ ki gbogbo awọn ti nka Iwe yi gbiyanju lati ka Iwe Ijala, nitori yio le mu wọn m itan ati jọ ere awọn Ọdẹ.

Emi ni
J. SANNI
badan.

## Ọrọ Ipinlẹ Igbomina Nkọ?

Inu mi yio pupọ bi Olotu ba jẹ gba mi ni aye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati ba awọn ọmọ iya mi sọrọ atata nipa Ipinlẹ ti a ti nja fun lati ọjọ pupọ sẹhin, a ko gbọ nlọ ati nbọ ọrọ na mọ rara.

Ẹ mọ jẹ ki o rẹ nyin rara t i aba k yesi ọrọ ti ọkan ninu awọn o nsclu wa sọ ni Iwọ-Orun, o ni ete ẹgbẹ ti on b i koba b ọ si ni oju on, bi ṣan ba ku t a n awọn ọmọ ẹgbẹ on yio gbe e t e na yori.

Nitorina e jẹ ki atẹle apẹrẹ yi bi awa ti a nawo nara yi ko ba le gba Ipinlẹ Igbomina loju ẹmi wa, dajudaju awọn ọmọ wa yio gba Ipinlẹ Igbomina.

Lagbara Oluwa awa ni yio gba Ipinlẹ na fun ara wa ti a w ọ n ọmọ wa yio si ba lọwọ wa.

Ibẹrẹ kiṣe oniṣẹ, ọrọ Ọlọrun ni, ẹniti o ba foriti titi de Opin ni ao gbala. Ẹ jẹ ki a foriti titi ti ao fi gba Ipinlẹ Igbomina.

Olotu Ọlọrun yio bo asiri nyin o.

Emi ni,
OLOKỌ ỌBA,
Mushin

## Awọn Ọmọ Jaguda Pọ Ni Oyingbo

Olotu, Inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye ninu Iwe Irohin yin oloyinmọmọ yi lati b a awọn Igbimọ ilu Eko sọrọ.

Ọrọ mi na ni lori awọn ọmọ Jaguda ti wọn di "Sango Ode" ma awọn ero ti o na ọja Oyingbo lọwọ.

Awọn jaguda yi ko tilẹ bikita pe ilu ti Ijọba wa ni awọn wa rara ọpọlọpọ nwọn ma saba fi ọwọ lalẹ larin ọja yi bi ẹnipe awọn lo kọ gbogbo isọ ti owa nibẹ.

Afẹ ki Igbimọ Ilu Eko se amujuto niparẹ lasiko.

Ti Igbimọ yi ko ba ṣe ohun ti oyẹ nipa ọrọ mi yi yio jẹ ohun ti yio ma doju ti wa gẹgẹ bi orile-ede.

Mo dupẹ lọwọ nyin Olotu iwaju lẹ o ma lọ o.

Emi ni
BABATUDE MARTINS
Ebute-mẹtta

## Igbaja Nfẹ Atunṣe

Olotu ẹdakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin alaka gbadun ti njade lojojumọ afi ọjọ isnmi lati ba Ijọba Ipinlẹ Ariwa sọrọ paapa awọn ti ntọju ilu Igbaja lori ipo ti ilu na wa ni asiko yi.

Gbogbo awọn oju ọna wa ti a gbẹkẹle ti baje patapata bẹ ni ako dakẹ lati mọ kesi Ijọba rere Ipinlẹ Ariwa pe ki nwọn wo ọla Anabi wa ki wọn ba wa tun oju ọna wa na ṣe.

Ilu Igbaja ki tapa si ofin Ijọba bẹna ni ako fi owo ori jafara rara, gbogbo ọmọ ilu Igbaja ni o mọ san owo sapo Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni asiko.

A nfẹ ki nwọn ba wa tun ilu wa ṣe bi nwọn ti tun awọn miran ṣe ni Ipinlẹ Ariwa.

Bẹna ni mo tun nbẹ Ijọba Ilọrin ki nwọn ba wa yọ ọda si oju ọna wa na bi ojo ti nbọ yi gbogbo ọna na kiṣe rin fun mọto rara, enia paapa kole rin ọna na ni asiko ojo ati ẹrun

Emi ni
ALHAJI SUNMỌNU
Igbaja

## Akyiesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe gbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara!

Awọn Egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu ko le ṣe Iwosan wọn lailai afi ki o ri ojulowo Egbogi "Ikọ" ti o ba lagbara gidigidi lati le hu Ikọ na lati ibiti oti joko si ti o si ti gbilẹ. Fun awọn iru Ikọ bẹ yẹn bere fun egbogi wọnyi:

### "Thmo-Ephedrin" Tabi Egbogi 'Linituss'

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ agbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki enia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsan ati loru-gbiyanju lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara gidigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri.

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma jẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ri yẹn Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogboẹda patapata" Amin.

**"WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

BI O BA NI
# Iwe—Titẹ
*FUN*
**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi oriṣiriṣi iwe itufọ tabi ijade Oku**
*ATI*
**IWE Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO *PỌKU* NI A *SI NBGA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Danwa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

## Awọn Kọ Mọsalasi Ẹdẹ Pari

ẸDẸ:— Ọpẹ fun Oluwa ni Oke Ọrun fun dida to da wa si tí nwọn si kọ Mọṣalaṣi na pari loju ẹmi wa. A dupe pupọ lọwọ awọn ti nwọn ṣe atilẹhin fun wa ti a fi yori Mọṣalaṣi na, a dupe lọwọ ile Mẹmi to ṣoju ẹhin lori rẹ awọn ile miranni, Ile Akaye, ile Imale, Ile Talafia (Ile Imam Oni) ati Ile Lakonu.

Anu ṣe wa lati tufọ ẹniti o jẹ Alaga Mọṣalaṣi na ti o di Ologbe, ki Ọlọrun ba wa pa aṣiṣe rẹ mọ, ko ba wa tẹ si afẹfẹ rere amin.

A dupẹ lọwọ ile mererin na fun wahala ti nwọn ṣe lori Mọṣalaṣi na, bẹna ni a tun dupẹ lọwọ Alfa ilẹ Oliyọbi, awọn ni nwọn ṣe gbo kegbodo ti a fi kọ Mọsalaṣi na pari.

A dupẹ lọwọ awọn iya Suna ti o wa ni Ẹdẹ nwọn fẹran ẹsin pupọ, bi a ba ni a nfẹ nkan lọgan wọn ti fun wa, ati yanrin ati okuta ni nwọn nfun wa lati fi kọ ile Oluwa na. Oluwa ko ni tu aṣiri nyin o. Bẹna ni Alfa gẹgẹ Ọlọrun yio gbọ adura nyin.

Ni ọjọ ti a kan Mọṣalaṣi na, Awọn Alufa Ẹdẹ ṣe gudugudu meje ni ọjọ na. Odidi ẹran ni awọn ara ile Akaje pa. Lati fi idunnu wọn han ati lati fi ran iṣẹ Oluwa lọwọ.

Ẹnu kọ irohin ni inawo ọjọ na, awọn ara ile Imae nawo, nwọn nara, nwọn ṣe onjẹ rẹpẹtẹ ni ọjọ na, ajẹti ati amuti ni nwọn fi onjẹ ati ọti aladun ṣe ni ọjọ na. Awọn ti nkọja lọ lasan nwọn yo gan ni, gbogbo adugbo ni nwọn ha onjẹ ka.

Bẹ ni a tun dupẹ lọwọ awọn ara ile Imamu fun inawo ọjọ na. Adupẹ lọwọ Oluwa fun Mẹkka ti Imamu nlọ ni ọdun ni, alalọbọ ni Ọlọrun yio ṣe o. A tun gbadura fun awọn ti yio lọ ni ọdun yi ki Ọlọrun sọwọn lọ ki o tun so wọn bọ amin.

Ki Ọlọrun ba wa tun ilu Ẹdẹ se o, ki a le tun mọ ni alafia, idẹra ni ilu Ẹdẹ o amin. A tun gbadura fun ilu yio ku. Ọlọrun yio wa pẹlu gbogbo wa amin.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 21 - Feb. 19) Jẹki gbogbo nkan ti iwọ yio ṣe loni yi jẹ pataki lori owo ati iwa rere ki o ma ba si darudapọ fun ọ.

PISCES (Feb. 20 - March 20) Mura lati ṣe iṣiro gbo gbo dukiya rẹ ki o si mọ iye ti o ni lọwọ, bibẹkọ, nwọn o gbe jibiti le ọ lọwọ.

ARIES (March 21 - April 20) Ọrọ rẹ kan yio huwa ti ko tọ si ọ loni, ṣugbọn tọju inu ile rẹ ati ẹbi rẹ ki o si ma a wo o niran.

TAURUS (April 21 - May 21) Jẹki ipokipo ti oba wa lẹnu iṣẹ rẹ tẹ ọ lọrun. Ọkan ninu ohun ti o ngbero yio yọri si rere laipẹ ni suru diẹ si i

GEMINI (May 22 Jun. 21) Osẹ yi yio ko ayọ wa ba ọ ṣugbọn ṣe pẹlẹpẹlẹ nibi iwa ti ko wọ ijọ ti o maa nhu lẹkọọkan.

CANCER (Jun 22 July 23) Ṣe ọjọ oni lọjọ faaji igbadun ile yio sele si ọ ati awọn ẹbi rẹ.

July 24–Aug 23 LEO – Iwọ yio ri irohin kan gbọ nipa owo nibi iṣẹ rẹ. Maṣe fa ijọgbọn loni yi ki awọn onijibiti tabi ọmọ jaguda o ma ba gba owo lọwọ rẹ.

Aug 24–Sept 23 VIRGO Bi o ti ndara fun ọ, ti o dabi ẹnipe, gbogbo aiye wa ni ikawọ rẹ loni maṣe fi ayọ ayọju ba ara rẹ jẹ. Eṣọ di owọ rẹ o.

Libra (Sept 24-Oct 23) Igbadun ati ayọ yio jẹ tirẹ loni yi ilọsiwaju yio si wa ninu iṣe ti o ṣẹṣẹ dawọle.

Scorpio (Oct 24-Nov 23) Iru ọjọ bayi ni o fẹran gbogbo iṣe si rẹ yio nitẹ lọrun.

Sagittarius Nov. 24-Dec 22) Ọrọ idunnu ti o sọ dun mọ ẹniti o sọ fun, iwo yio si ri ere nla jẹ nibẹ.

Capricorn (Dec 23-Jan 20 Iwọ yio ma ri awọn ohun ti ko dun mọ ọ ninu ni akoko owurọ ṣugbọn akoko ayọ ni ọjọrọ yio jẹ fun ọ.


## AKARA TU S'EPO!

### Iwe Itumọ Ala na ti de !!



Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

J. Ọ. SHOYINKA
N?/99 Shittu Street
Ibadan

BERE OJULOWO EGBOGI:—

## Congreve's Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titu fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirnu nigbakugba tabi ni ẹkọnkọn ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ejẹdudu lara tabi aikofọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba-aiya riru ọmu riro wiwo, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi-oju Ilaogun ara jẹ ẹsẹ ara sisọn, gbori abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun tọju gbogbo Obinrin gegebi Ajo fun ilera idi nọ ati orisirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## mmoniated Quinine Tincture

Nigba Isilai ki awọn Orisirisi sọbirọki egbogi ti wọn uko wa isisinyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi iwe egbogi yi bi otutu kọ ira, orẹrẹ lukuluku onigbameji aibui ba nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danju ni bi oba ti ta de sini omi ti o bọwosọ ki o si gbe u sare egbogi otutu ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, to Akokoro, egbogi ti o ma njọ apo-ie-itọ tabi se iwosan iyọuu ayọ-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọwa-ọfun didun ati orisirisi omiran pẹlu bere ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Mdicine Stores
8 Palm Chuch Street, Lagos.
Phone: Nigeria, (Oja Ita Faji)

# Ko Si Ẹniti o Fẹ Fẹ Mi

Mo jẹ Ọmọbinrin Ọmọ Ọdun mẹẹdogun Ọyan mi si tobi pupọ ju ti o fi jẹ pe o nyọ mi lẹnu ninu igbesi aiye mi, nitori eyi nko le jade nigbakugba ileni mo maa, ko si ẹniti o fẹ fẹ mi.

Jọwọ Iyaafin Ayọka kini ki nse ti ngo fi ni Ol - fẹ tabi Dokita le ran mi lọwọ nipa re bi ?

Emi ni
Omidan Sidikatu
IBADAN

IDAHUN:—
Omidan Sidikatu O le ma ni Ore ti o ba nro bi o ti ri tabi bi Ọjọ ori rẹ ti to ti o ko ba si tun njade. Sugbọn nipa ti Oyan rẹ, ti o sọ pe o tobi ju o le jẹ pe o sanra ju, nitori eyi mo gba ọ ni imọran pe ki o lọ ri Dokita, ki o si bere fun iru onjẹ ti o yẹ fun ọ, lati ma jẹ. Fun igba diẹ lọ ra aṣọ ti awọn Oyinbo fi nkọ Oyan soke (*Brassiere*) ki o si ma lọ.

EMI KO NṢE OṢO

Mo jẹ ẹni Ogun Ọdun, mo si ti gbe Ọmọ Ọdun mẹrindinlogun ni iyawo. Anu ṣe rai pe aya mi na ku lẹhin ti o bimọ tan, lati igbana ni awọn Ọmọ. debinrin ti o ku ni ilu wa ti nsa fun mi ti mo ba pe wọn, nwọn si maa nsọ pe Oṣo ni mi. Jọwọ fun mi ni imọran bi awọn ti ṣe le mu ero yi kuro ni ọkan wọn ti awọn o si ma da mi lohun ti mo ba ti pe wọn.?

Emi ni,
RASAKI
Oshogbo

IDAHUN:- O jẹ iyalẹnu fun mi pe gẹrẹ ti iyawo re ku ni o ti tun nle awọn ọmodebinrin kiri, O yẹ ki o fun ara rẹ ni asiko, di igbati o to pade ẹniti o ni ifẹ rẹ gan an Bi o ba ni suuru, O ri ọmọdebinrin ti ifẹrẹ yiò fẹ lati fẹ ọ. Amọran temi si ọ niyi o.

AKIYESI:- Ẹnikẹni ti ohunkohun ba ru loju nipa igbesi aiye rẹ tabi nipa iyawo afẹsọna tabi larin ohun ati awọn ẹbi rẹ paapa nipa ihu wa si rẹ ninu awọn olubagbe rẹ ki o kowe si Iyaafin Ayọka, c/o 16, Bamgboṣe St., Lagos, ngo si fun oluwarẹ ni Imọran ninu Iwe Irohin Imọlẹ.

Ẹ jọwọ ki ẹ ma a kọ iwe nyin ki o ma a hanketekete ki asi le ri iwe na ka daada
Ẹku iṣẹ o.

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI a ti fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, awọn ti tu ẹgbẹ Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ nitorina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ ti tun yi ki o kowe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran. Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma ṣe.

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọrọ sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ojogbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo Iṣẹ, Draft Lude Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ẹ o ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi, ki o wa si ipade ọjọ 11/4/64 ni nomba 16, Bamgbose St., Lagos, Ao si tun yan awọn aluṣẹ ẹgbẹ titun.

Eyi ni oruko awọn Igbimọatunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ola. Okunọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abdulahi Awẹlẹnjẹ
5. Timoty Akins

E jọwọ, ẹ tete de ipade ẹ.

AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**
*PRESENTS*
**An Eid-Ul-Kabir Dance**
AT
**FORESTER CENTENARY HALL**
22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn.

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ Offices, Wemimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta.

BERE OJ... ...O EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjuọwo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Tatambulu si Itali je.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Eṣe Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo, iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu

Bere egbogi ajẹbina Payal yi ni ṣọbu wọnyi:—
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Fai)
(2) Adedun Chemist
4, Wakeman Street, Yaba

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 564 WEDNESDAY MARCH 25, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.

# KANSILỌ KAN WEWỌN ỌDUN MEJI

ONITSHA:- Ọkan ninu awọn kansẹlọ ilu Onitsha ni irohin fi ye wa wipe adajọ kotu kan nilu n a ti ju si ẹwọn ọdun meji fun ẹsun pe ọgba owo abẹtẹlẹ.

I r o h i n fi ye w a pe Kansẹlọ n a ọgbẹni James Arene ni a gbọ wipe ọ gba pọnun mọkanlelogun (£22) lọwọ onimọto kan, Samuẹl Anarodo ninu o ṣ u kẹrin ọdun ti o kọja yi.

Agbọ pe Kansilọ na gba owo yi lati le ṣ e agbara fun onimọto yi lati le ma jẹ k i awọn m ọ t o rẹ jẹ bọọsi larin ilu Onitsha.

Irohin kan tun fi ye wa wipe ọdọmọkunrin kan John Udo ti e nṣiṣẹ agbawọ ni adajọ kotu Ikẹja ti ju si ẹwọn ọdun kan fun ẹsun pe o fi ọ g b ọ n gba owo pọnun mẹwa s i l e maruu (£10:5/-) lọwọ S u n d a y Udonaw.

Agbọ w i p e John Udo yi fi ọgbọn gba o w o yi ti o sise ile ri pe on y i o ṣe agbara fun Sunday lati le ri iṣẹ Akọwe labẹ awọn ti nse panu ikọle ni Ikẹja (Alumilum Industry.)

Nigbati ọ daran na rojọ ti o si gba wipe on jẹbi ni ni adajọ ba ṣe idajọ pe ki o lọ fi ẹwọn ọdun kan jura.

## Igbimọ Musulumi Ti Ilu Eko

Lati Oju Ewe Kini

lọ si Mẹkka ati Mẹdina lọdun yi dupẹ mẹwa-mẹwa fun Ọlọrun.

Lẹhin ti nwọn dupẹ tan o tun sọrọ rẹ kin Alhaji Yakubu lẹhin wipe:- Nitotọ odi Ọdun kọkandilogun, ti on ti nlọ si Mẹkka ati Mẹdina gẹgẹbi iṣẹ ti Ọlọrun pin mọ on.

O ni pẹlu aṣẹ Ọlọrun ati atilẹhin Ojiṣẹnla Mahammed,O ni kosi ẹnikan ninu awọn ti o ba on lọ ti Oluwarẹ koni pada dele wa ro hin on si rere.

Alhaji Kafo pari ọrọ rẹ wipe. kosi ohun ti o nmu enia lọ ti o si tun umu enia bọ ti o ju owo; Igbẹkẹ le ododo si Ẹlẹda rẹ ati ọpọlọpọ adura atọkanwa: O ni iṣẹ ti on lọhun ni wipe, ki Oluwarẹ ko maṣe si inira tabi ipọnju to le ko aisan baa titi yio fi pada dele rẹ.

KO SI EWU NI MẸKKA

Lẹhin ti Alhaji Ralfos sọ tirẹ tan ni Alhaji Lateef Tẹniọla (Oniwe Irohin) abi gege ku bi ọjọ dide, on fi nye awọn ọmọ ẹgbẹ na to nmura lati lọ si Mẹkka ati Mẹdina lọdun yi wipe-kosi Apania tabi, ohun ipalara kan ni Mẹkku ati Mẹdina.

O ni, bi ẹba gbọ wipe nkankan ṣe enia kan lohun, oni ki nwọn o mọ wipe, Afọfa ẹni na ni.

Alhaji Tẹniọla sọ wipe nitotọ. Orun to nran lọhun o yatọ si ti wa nihin. depo wipe bi ogun na ti pọ to ọpọlọpọ ni awọn enia ti nwọn ma nde yinyin mọ fila wọn. O ni awọn ti o nde yinyin mọ fila yi, jẹ awọn Olofintoto, ti nwọn ko le joko si ibudọ wọn.

Alhaji Tẹniọla fi n y e ẹnikẹni nii u apejọ ọjọ na wipe; bi ori ba nfọ ọ, tabi arẹ nfẹ mu ọ, o ni, Dọkita wa fun itọju ẹnikẹni.

O ni, awọn ti ẹ ngbọ iku rẹ yen jẹ awọn ala— rinkiri, ti nwọn ko bikita fun ẹmi wọn. Alhaji Tẹniọla pari ọrọ rẹ w i p e, "kosi ewu kan kan nibẹ, ayafi ẹniti o ba nfẹ ri eyi, ki o tun lọ ri tọhun".

ADURA LOGUN MẸKKA

Bi Alhaji Tẹniọla ti mba ọrọ rẹ dele, bẹni Alhaji A. F. Masha (Alaga Igbimọ Ibile Eko) dide, on na tun sọrọ kin ọrọ Alhaji Tẹniọla lẹhin.

O ni Adura lo yẹ ki gbogbo ero to nlọ si Mẹkka ati Mẹdina o ma a ṣe. Ki awọn ti o jẹ enia wọn nile na o tun ma a fi Adura atọkanwa ba wọn lọ, nitori pe, ko si ohun ipalara kan nibẹ.

Alhaji Masha ni, bi ẹ ba gbọ wipe, nkankan ṣe ẹnikan lọhun, o ni, ki ẹ mọ daju wipe, awọn Olofintoto ti nwọn nfẹ ri JABATORO ati JABATẸRẸ ni.

Awọn t i nwọn nmura lati lọ si Mẹka ati Medina ọdun y i t i wọn ọ m ọ ẹgbẹ Igbimọ Musulumi ṣe Ariya na fun ni awọn ẹni bi:

Alhaji A.F. Masha (Alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko) Alahaji Tẹniọla (Oniwe-Irohin) abi gege ku bi ojo Alagba Y u s u s Adeshina (olori ẹgbẹ ọmọ-Ijaye Eko) Alufa Asani O p e (I b e j i Imam Oseni Ope) Ọgbẹni M.I. Onigbanjo (Kansẹlọ Igbimọ Ijọba I b i l ẹ Eko) Iya-Afin Ashiawu A. Ajadi; Iya Afin Sabitiyu Oshodi ati awọn enia jankanjankan Mirau.

Diẹ ninu awọn Sanmọri ọmọ ẹgbẹ na to peju pere sinu ipade na niyi:- Ọmọ-Ọba A L A. Ọjora; Ọmọ-Ọba Adeniran Adefarakan; Ọmọ-Ọba Awdu Akinyẹmi; Alhaji A. K. Bello; Alhajia Falilatu Bello ati ọpọlọpọ Alhaji ati Alhaja

Adura awa oniwe Irohin-Imọlẹ si ẹnyin ero Mẹkka ati Mẹdina na n i wipe-Ki a lo o dara, ki abọ nyin o dara pẹlu

K i Alah mu nyin lọ layọ ki o si mu nyin pada b ọ wa sile, o dabọ o

Lati Oju Ewe Kini

Nigbati awọn fi Oloye na jẹ oye tan, ni gbogbo awọn ẹbi, ọrẹ, iyekan ati ojulumọ wa bẹrẹsi ṣe are orişirlşi ni arin ode gbangba Ile Oloye na titi ile ọjọ keje fi fẹrẹ mọ kedere.

Ọgbẹni A. B. Irọkọ ti iṣẹ akọbi Oloye na ati awọn aburo rẹ na wabiwọsi owo ni ọjọ na

Bi awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ti pọ to ajẹti ati amuti ni awọn enia na fi onjẹ ṣe. Awa Oniwe Irohin Imọlẹ ki baba wa Oloye D. O. Irọko ku orire, ti o di Olori awọn elegungun ilu Eko agbegbe rẹ.

A jẹ gbo, a jẹ tọ Ọkọ ọba ko ni ṣe nyin lẹṣẹ,


Pinted and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) P. O. Box Bariga (25/3/64)